# ITUMO KI A NI AGBOYE ESIN ISLAM PELU AWON ERI

[ Yorùbá -Yoruba - يوربا ]

**Igbimo iwadi ijinle lori imo esin ati idahun fun ohun ti o ruju ninu esin ni ilu Saudi Arabia**

**Eni ti o tumo re ni:** Rafiu Adisa Bello

2014 - 1435

IslamHouse.com

# معنى معرفة الإسلام بالأدلة

« بلغة اليوربا »

الرئاسة العامة للبحوث العلمية والإفتاء
في المملكة العربية السعودية

ترجمة: رفيع أديسا بلو

2014 - 1435
IslamHouse.com

# ITUMO KI A NI AGBOYE ESIN ISLAM

# PELU AWON ERI

**IBEERE:**

Kinni itumo gbolohun eni ti o ko tira ti oruko re n je (Haashiyatul Usuul As-salaasa) nigbati o so wipe: "O je dandan ki a mo esin Islam pelu awon eri"? O si tun so ni aaye miran wipe: "Olohun ran ojise kan si wa, eni ti o ba tele e yoo wo ogba idera (Al-janna), eni ti o ba si yapa ase re yoo wo ina". Se ohun ti eleyi tumo si ni titele ojise Olohun abi sise Olohun ni okan soso nibi awon iroyin re?

---

**IDAHUN:**

Itumo oro eni ti o se tira ti a daruko yi nigbati o so wipe "O je dandan ki a mo esin Islam pelu awon eri" ni wipe: O je dandan fun eni ti a ti la iwo bo l'orun (eni ti o ti balaga) pe ki o ko eko nipa awon origun esin Islam lati ibi ti o je orisun ti o ti ye ki a ko oro esin, awon nkan naa ni tira Olohun Al-kurani Alaponle ati sunna ojise Olohun- ike ati ola Olohun ki o maa ba a. Ki o ko eko nipa mimo Olohun ni okan soso (Taoheed) ati ohun ti o maa n ko aaye ba a ati ohun ti o maa n ba a je patapata. Ki o ko eko nipa irun kiki ati awon majemu re ati awon origun re ati awon sunna re, ki o ko awon nkan wonyi ninu Al-kurani Alaponle ati lati ibi awon oro ojise Olohun ti o wa ni akosile ati

awon ise re ati awon nkan ti apakan ninu awon omoleyin ojise se ni oju re ti ko si ko fun won. Bayi ni o ye ki Musulumi maa ko nipa awon origun esin Islam ti o ku ati awon ofin esin naa.

Bakannaa gbolohun re ti o so pe "Olohun ran ojise kan si wa, eni ti o ba tele e yoo wo ogba idera (Al-janna), eni ti o ba si yapa ase re yoo wo ina" itumo re ni wipe: Olohun- Oba ti O ga julo- gbe Anabi wa Muhammad dide ni ojise pelu mimo Olohun ni okan soso (Taoheed) ati awon ofin esin yoku, eni ti o ba je ipepe re ti o gba esin Olohun, ti o si tele awon ofin Olohun naa, ti o si jinna si awon ohun ti Olohun se ni eewo fun un irufe eni bee yoo wo ogba idera. Sugbon eni ti o ba ko, ti ko gba esin Olohun, ti o tun tapa si ofin ojise Olohun ati ilana re irufe eni bee yoo wo ina. Idi niyi ti Olohun- mimo fun Un- fi so ninu Al-kurani wipe: {Enikeni ti o ba tele ojise naa, lotito o ti tele Olohun, enikeni ti o ba si peyinda (ti ko tele e), Awa ko ran o (ire Anabi) pe ki o je oluso le won lori} [Suuratu Nisaai: 80].

Ni afikun, o tun wa ninu hadiisi ti ojise Olohun so wipe: "Gbogbo ijo mi ni yoo wo ogba idera (Al-janna) ayafi eni ti o ba ko", awon omoleyin re si beere wipe: Tani yoo ko ire ojise Olohun? Ojise Olohun wa so bayi pe: "Eni ti o ba tele ase mi yoo wo ogba idera (Al-janna), eni ti o ba si yapa ase mi irufe eni bee ti ko lati wo ogba idera (Al-janna)" [Bukhari: 7280].